Bibeli fun awon omode



# Ologbon Oba Solomoni

Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Oba Dafidi je alagbara ninu Oluwa. Lasiko ise joba re, Israeli dagba ni ilopo mewa ju ise joba Oba Soolu lo. Sugbon nisinsinyi ko le se ijoba mo. Dafidi di arugbo, o ti re e! O si saisan! Igbe aye re lori ile aye ti n sunmo opin.





Ninu awon omo Dafidi, Adonija, so fun awon omo Isreali oun o di oba nisinsinyi.  Bi o tile je pe oruko re tumo si "Oluwa mi ni Olorun."  Adonija ki se eniyan daradara.  O ngbiyanju lati ja ijoba gba, nitori o mo pe Dafidi ko ni agbara mo lati ta koo. Sugbon Olorun ni ona miiran.

Batisheba iyawo Dafidi mo pe Solomon omo re lo ye ko joba, O so fun Dafidi nipa erongba Adonija.  Sibe ara re koya, Dafidi pe gbogbo awon agbaagba re o si kede Solomoni gegbe bi Oba Israeli.



Solomoni ko ni isoro pupo pelu Adonijah tori pe awon omo Isireli gbagbo ninu Dafidi.  Dafidi so fun won pe Solomoni ni eni ti Olorun yan gege bi Oba won. Leyin igba die si i, Dafidi ku.





Ki Dafidi too ku, o so fun Solomoni nipa gbigboran si ase Olorun ki o si je Oba rere. “Rin ni ona Olorun, ki o o le dara fun o ni ohun gbogbo ti o ba n se”, Dafidi so fun omo re. Imoran ti o dara niyen! Leyin igba naa Solomoni joko lori apere baba re, Dafidi, ijoba re si fi idi mule.

Lale ojo kan, Solomoni la ala. Ninu ala re, Olorun farahan an, o si wipe "Beere! Kinni o fe ki n fun o?" Kinni o fe ki n se fun o?



Solomoni beere fun ogbon lati je oba rere, ohun ti oba ti oba kekere yi bere te olorun lorun. Solomoni gba ohun ti o beere lowo Olorun, Sibe, Olorun tun waa seleri oro ati ola fun-un.





Ko pe ti awon eniyan fi ri Ogbon Solomoni.  Ni ojo kan, awon obinrin meji wa si iwaju re, pelu omo kan, omo obinrin yii ku ni oru o si gbe oku omo dipo alaaye temi, obinrin kan wi pe “Rara!  Sugbon eyi alaaye ni omo mi, eyi oku ni tire”, eyi ekeji wi pe. Bawo ni Oba o se so pe eyi ni iya omo tooto?

Nigba naa ni oba wi pe "E mu ida fun mi" won si mu ida wa siwaju oba.  Kin ni o le ro pe oba yoo fi ida se?



Oba si wi pe, "E la eyi alaaye omo si meji ki e si fi idaji fun okan ati ekeji re." Obinrin ti alaaye omo n se tire wipe, "Oluwa mi, e fun un ni alaaye e mase paa rara."



Sugbon eyi keji wi pe,
"ki o mase je temi tabi
tire, e pin si meji".





Oba dahun wi pe, “E fun obinrin akoko ni alaaye omo, oun ni iya re.” Gbogbo omo Isreali si gbo idajo oba, won si bowo fun oba. Won ri i pe ogbon Olorun wa ninu re!

Awon omo Isreali ko ni tempili tiwon yio fi maa josin fun Olorun. Dafidi gbiyanju lati ko okan, Olorun si wi pe "Omo re ni yoo ko ile ni ORUKO MI." Nitori naa Solomoni bere lati ko tempili ni Jerusalemu.



O si gbaa ni Odun meje
ko to ko tempili naa.
Sugbon ojo nla naa
de ti gbogbo eniyan
pejo lati ya tempili
naa si mimo
fun Olorun.



Leyin adura, oba ati awon eniyan fi tinutinu rubo fun ose meji.



Leyin naa, Olorun tun farahan Solomoni o si seleri lati bukun un ati Isreali niwon igba ti won ba gboran si OLUWA.





Pelu Ibanuje boya Solomoni tabi awon eniyan Isireli gboran si ase Olorun ni gbogbo igba. Oba fe awon iyawo eyi ti Olorun ko fe ki o fe. Awon iyawo yii yi lokan pada lati to orisa leyin, okan re ko si se deedee niwaju OLUWA Olorun re, gege bi okan Dafidi baba re.





Nigba ti Solomoni ti fi asiko re sofo lati gboran si Olorun, ijoye re kan ti Oruko re nje Jeroboamu ni imolara iriri to yato. Woli kan so fun un pe Olorun yoo pin ijoba Solomoni ati pe Jerobamu yoo joba lori mewa ninu eya mejila. Jeroboamu yara sa lo si Egipiti. O mo pe Solomoni yoo pa oun ti oun ba duro.





Paripari, Solomoni ku, omo re, Rehoboamu, gbe ajaga ti o wuwo ju ti Solomoni lo le awon eniyan lori ju bi solomoni se se lo. Eya mewaa sote... won si yan Jerobamu ni olori won. Ijoba alagbara Solomoni pin si meji, gege bi woli Olorun ti so. Olorun ko le e bukun alaigboran.

# Ologbon Oba Solomoni

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Awon oba kinni, ori kinni si Ikejila

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.